(FRONT COVER)

# Ó RÉKỌJÁ ÒMÌNIRA

**Ó dá lórí àwọn ìdánilẹ́kọ̀ àwọn ìwé mímọ́ Vedic ti India tí ó wà láíláí**

Ìwé pélébé yi wa fun awọn ti o nwa awọn ìgbékalẹ̀ ti o tọ̀nà laye, agbara ojulowo ìfẹ́. Agbara yi kọja igbadun awọn ohun ti ara ti ó si ga ju ominira miran lọ. O jẹ́ ipa alagbara ti o le gbé eniyan de àyè ti ẹ̀mí, ibiti o jẹ́ wipe ìfẹ didun ati ìrẹ́pọ̀ wà.

Gbogbo ironu ibẹru, eyiti ó lodi le pòórá nipase oye ìdánimọ̀ wa ninu ẹ̀mí gẹ́gẹ́bí iranṣẹ ti o ni ibaṣepọ pẹ̀lu ẹniti ó ga julọ. Eyi kii ṣe idanimọ ti ara ti o si rekọja ohun ìmọ̀lára.

Ninu ọ̀rọ̀ Ọlọ́run, àkókò kò já mọ́ ohunkohun: ohun gbogbo ati gbogbo eniyan ni wọn lè wà ní àìkú. Ayé ti ẹ̀mí yi kun fun ẹwà, ó jọjú pẹ̀lú Alafia.

"Ó rékọjá Ominira" tan ìmọ́lẹ̀ si oniruuru ọ̀nà ti a nrin ninu aye ìgbà díẹ̀ yi nígbàtí a nwá ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ ìdùnnú.

Gbogbo ọ̀rọ̀ inú ìwé yi wá tààrà láti inu àwọn àkọsílẹ̀ Vedic àtijọ́.

# Ó RÉKỌJÁ ÒMÌNIRA

**Ó DÁ LÓRÍ ÀWỌN ÌDÁNILẸ́KỌ̀ ÀWỌN ÌWÉ MÍMỌ́ VEDIC TI INDIA TÍ Ó WÀ LÁÍLÁÍ**

## Àwọn Àkòrí inú Ìwé yì

ỌRỌ̀ ÀKỌ́SỌ ……………………………………………………….5
ÌFÁÀRÀ…………………………………………………………..6
ǸJẸ́ O LÈ FI ỌLỌ́RUN HÀN MÍ? …………………………………7
NIBITI A LÈ FI ÌFẸ́ ATI ÌGBÉKẸ̀LÉ WA SÍ ……………………...9
ǸJẸ́ AWỌN ÈRÈ TI ARA LÈ MÚ OJÚLÓWÓ ÌDÙNNÚ WÁ BÍ?10
ÀWỌN ÈRÈ TI ARA KÌ Í ṢE IPA TÍ Ó TAYỌ JÙLỌ ……………10
IPA Ọ̀NÀ ÒMÌNIRA ………………………………………………11
ÌRÒNÚ LÓRÍ ÀKÓKÒ ……………………………………………12
Ó RÉKỌJÁ ÒMÌNIRA ……………………………………………..13
KÍNI ÌFẸ́ TÒÓTỌ́? …………………………………………………13
IPA ÌFẸ́ ÀTÒKÈWÁ ………………………………………………14
NÍBITÍ A TI LÈ RÍ AGBÁRA ……………………………………..14
ÌFẸ́ ÀTI ÌBÁRA ẸNI ṢE PAPỌ̀ ……………………………………15
BÍ A TI ṢE LÈ ṢE ÀṢÀRÒ ………………………………………...15
NÍ ÀKÓTÁN ………………………………………………………16

## *ÒRỌ ÀKỌ́SỌ*

Awọn Vedas jẹ́ àwọn iwe mimọ́ ti India atijọ, eyiti ó ní oniruuru ọgbọ́n ti èniyán mọ̀. Lotitọ, gbogbo ìmọ̀ ní gbogbo ìpìlẹ̀ lè tọ ipasẹ̀ orísun wọn padà lọ sí awọn akọsilẹ̀ wọnyi. O dahun àwọn ibeere eniyan nipa ìtọpinpin idunnu ti ara, ìlépa ìgbàlà nipasẹ ominira ati pẹ̀lu ipa ìwá- ara- ẹni- rí nipasẹ ojulowo ifaraji fun iṣẹ́ Ọlọrun. Vedas ṣe apejuwe ìpéye Ọlọ́run ati ẹniti Í ṣe, dídára rẹ̀ ati oniruuru agbara RẸ̀. Ìbẹ̀rẹ̀ ati ìdàgbà rẹ̀, akọsilẹ̀ ayeraye yi ti di àtọwọ́dọ́wọ́, ko yipada, kò ní àbùkù, ó wà ni ipò pípé àtètèkọ́ṣe rẹ̀, lati ọ̀dọ̀ Ọlọrun lọ sí ọ̀dọ̀ olùkọ́ dé ọ̀dọ̀ akẹ́kọ̀ gẹ́gẹ́bí okùn tí kò lè já.

Opin gbogbo ohun ti ó ṣeé ṣe ni a ri ninu àwọn iwé mímọ́ Vedic; a le rí ìdùnnú ayeraye ti à nwá kakiri. Àwùjọ òde òní tí eniyan njiya ìrora ati ìpòrúuru ọkàn, ìjà ati ìbáṣepọ̀ ti ko dara, ojúkòkòrò ati àgàbàgebè. Ọ̀pọ̀ nṣe làálá láyé lati ri wipe nkan nlọ bi ó ṣe yẹ. Oungbẹ òtítọ́ giga ngbẹ wá, síbẹ̀ nigbagbogbo ni ọgbọ́n ati àìmọ̀kan giga wa nṣì wá darí.

## *ÌFÁÀRÀ*

Èrèdí ìwé pélébé yi ni lati yànnàná ipa mẹ́ta ti o dájú ti awọn eniyan ntẹ̀lé lati lè ni ìdùnnú láyé.

Ọ̀pọ̀ ènìyàn nwá ìgbádùn lati inu ohun ti o wà niwaju wọn ninu ayé, ohun ti oju lè rí ati lati inu oniruuru ìgbádùn. Ìdà keji ni lati kọ awọn ohun ti ara sílẹ̀ patapata kí a wá gba àbò lati inu Alafia tí a rí lati inú ọkàn. Ìkẹta, èyí tí ó jẹ́ ipa tí ọ̀pọ̀ kìí tẹ̀lé ni ki eniyan rin irin àjò nipasẹ ọkàn tí ó jí tí ó nwá láti mọ ìdánimọ̀ ìbáṣepọ̀ ayeraye rẹ̀ pẹ̀lú Ọlọ́run.

Àwọn itan wọnyi yànnàná pé ìlépa èyíkéyì ninu àwọn àfojúsùn wọ̀nyí nílò kí a tẹ̀lé àwọn ilana kan ni pàtó, gẹ́gẹ́bí tí a bá fẹ́ gba oyè agbejọ́rò, tí a níláti yege ninu awọn idanilẹkọ kan lati lè ṣe èyí.

## *Ó RÉKỌJÁ ÒMÌNIRA*

**NJẸ́ O LÈ FI ỌLỌ́RUN HÀN MÍ BÍ?**

Nígbàkan ni India, ọba kan wà tí ó fẹ́ rí Ọlọ́run. Ó ranṣẹ́ pe adari agba rẹ̀, o bèrè wipe, "Njẹ́ o lè fi Ọlọ́run hàn mí bí? Njẹ́ o lè sọ fún mi ní pàtó ohun tí Ọlọ́run nṣe? Bi ó tilẹ̀ jẹ́ wipe adarí yi jẹ́ ẹnití ó ka ìwé, kò lè tètè ronú ìdáhùn tí ó tó fún ìbérè ọba, ó wá bẹ̀bẹ̀ ki ọba fún òun ni ọjọ́ mẹ́ta lati ronú lori ìbérè tí ó tọ́. Ọba gbà, ṣùgbọ́n pẹ̀lú ìkìlọ̀ pé tí ìdáhùn tí kò bá tẹ́ òun lọ́rùn bá wáyé, yio dín ìgbàgbọ́ ọba ninu rẹ̀ kù gẹ́gẹ́bí adarí àgbà.

Adarí àgbà yi padà lọ si ibugbe rẹ̀ pẹ̀lú ìwádì tí ó jinlẹ̀ ninu awọn ìwé inú yàrá ìkàwé rẹ̀ pẹ̀lú ìrètí lati rí idahun ti ó tọ̀nà fun ìbérè ọba. Lẹ́hìn ọjọ́ méjì, kò Ì tíì sí àbáyọ. Bí ó ṣe jókò tí ó nronú ninu yàrá ìkàwé rẹ̀, ọmọ rẹ̀ tí ó jẹ́ ọmọ ọdún márùn gùn le lórí, ó wá bèrè, "bàbá, kíni ó dé tí ojú rẹ fi fàro?

"Èmi kò tíì rí ìdáhùn tí ó tọ̀nà fun ìbéèrè tí ọba bi mí, nipa bẹ̀, mo lè sọ ipò mi nù nínú iyàrá ìgbẹ́jọ́"

"Kíni ìbéèrè ọba?" ọmọ na bèrè.

"Kì Í ṣe ìbéèrè tí ó lè yé ọ gẹ́gẹ́bí ọjọ́ orí rẹ ọmọ mi, má da ara rẹ láàmú"

Ṣùgbọ́n ọmọ rẹ̀ kò dẹ́kun lati máa bèrè, nípa bẹ̀, níkẹhìn, adarí na sọ fun, "Ọba fẹ́ rí Ọlọ́run, kí ó sì mọ ohun tí ọlọ́run nṣe, mo ti wádì gbogbo ìwé mímọ́, ṣùgbọ́n èmi kò rí ìdáhùn tí ó tọ̀nà sí ìbérè yí".

Ọmọ kùnrin kékeré yì rẹ́rìn músẹ́ tí ó sì dáhùn, "Baba, èyí rọrùn. Tí o bá lọ sí yàrá ìgbẹ́jọ́ lọ́la, sọ fún ọba wipe ìdáhùn sí ìbéèrè yí rọrùn tí ọmọ kékeré rẹ gan lè sọ fún ọ bí o ti ṣe lè rí Ọlọ́run kí ó sì ṣe àlàyé ohun tí ó nṣe" Adarí àgbà yí wo ọmọ rẹ̀ lójú pẹ̀lú ìgbàgbọ́, Ṣùgbọ́n ọmọ rẹ̀ fi da lójú wípé "Má fòyà bàbá, mo fi dá ọ lójú wipe èmi kò ní já ọ kulẹ̀"

Adarí nà pẹ̀lú ìrètí kò ṣe iyèmejì ṣùgbọ́n o fi ìrètí àti ìgbàgbọ́ rẹ̀ sínú ọmọdékùnrin rẹ̀ yí. Ní òwúrọ̀, wọn jọ lọ si gbàgede ìdájọ́ ọba. Ọba gba adarí na wọlé, ó tún bèrè, "Adarí Pataki mi ọ̀wọ́n, njẹ́ o lè fi Ọlọ́run hàn mí kí o sì sọ ohun tí ó nṣe fún mi?"

Adarí ná dáhùn pẹ̀lú ìrẹ̀lẹ̀, "Ọba, ìbérè yí rọrùn tí ó jẹ́ pé ọmọ mi kékeré yì lè dáhùn rẹ̀".

Bí èyí tilẹ̀ ya ọba lẹ́nu, ó kojú sí ọmọdé kùnrin na, Ó wípé, "O káre, óyá, ọmọ mi, njẹ́ o lè fi Ọlọ́run hàn mí kí o sì sọ fún mi ohun tí ó nṣe?"

Ọmọdékùnrin na wípé, "Kábíyèsí, jọ̀wọ́ mú ìkòkò wàrà nlá kan wá".

Ìbérè yí ya ọba lẹ́nu, ṣùgbọ́n ó gbà.

"Kábíyèsí, ṣé ọ̀rá wà nínú wàrà yí?" èyí ni ìbérè ọmọdékùnrin yi.Ọba ronú díẹ̀. Ó dáhùn wípé"Bẹ́ni, ọ̀rá wà nínú wàrà nà" "Njẹ́ o lè fi hàn mí?" ni ọmọ nà bèrè.

"Bẹ́ni", Ọba dáhùn, "Ṣùgbọ́n ṣájú, kí a tó lè rí ọ̀rá nà, a níláti mi wàrà ná pọ̀ lọ́nà agbára"

Ọmọ na dáhùn wipe "Bẹ́ni"bẹ́ná ni ìlànà ti a fi lè rí Ọlọ́run wà. Nígbàtí a bá tẹ̀lé ìlànà ti ẹ̀mí, Ọlọ́run yio fi ara han wá. Laisi ilana ifaraji ìgbésẹ̀ ti ẹ̀mí yí, a kò lè rí Ọlọ́run ní tàrà, bẹ́ná ni ọ̀rá fi ara sin sí inú wàrà títí di ìgbàtí a mi wàrà nà papọ̀ pẹ̀lú agbára"

Bí Ọbá ṣe gbọ́ àlàyé ọlọgbọ́n sí ìbérè àkọ́kọ́ rẹ̀, ó tẹ́ Ọba lọ́rùn, ó wá bèrè lọ́wọ́ ọmọ na ìbérè kejì. "Bayi njẹ́ o lè sọ fún mi ohun tí Ọlọ́run nṣe?"

Ọmọ na wipe, "Ó dára, ò nbèrè lọ́wọ́ mi gẹ́gẹ́bí ọmọ akẹ́kọ̀ ṣe nbèrè lọ́wọ́ ọ̀jọ̀gbọ́n, ṣùgbọ́n ìwọ jókò lórí ìtẹ́ nlá tí ó ga, tí èmí sì jókò níwájú rẹ lórí ilẹ̀. Gẹ́gẹ́bí àṣà, ó yẹ kí ìwọ jókò ní ipò ìrẹ̀lẹ̀ kí èmi sì jókò sí ipò gíga"

Nígbàtí ó rí òtítọ́ ninu awọn ọ̀rọ̀ ọmọ na, ọbá dìde lórí ìtẹ́ rẹ̀ ó sì jókò sí ilẹ̀, tí ọmọ na sì jókò sí orí ìtẹ́.

"Èyí ni ohun tí Ọlọ́run nṣe", ni ọmọ nà wí. Nigbamiran, yio fi wa sí ipò gíga ati nigbamiran sí ipò ìsàlẹ̀, ni ibamu pẹ̀lú àwọn àbájáde àwọn ìṣe wa àtẹ̀hìnwá. Nigbamiran aó gba àyè ìbí tí ó ga, ati nigbamiran ibi tí ó lọ sí ilẹ̀. Ọlọ́run nṣètò nkan wọ̀nyí tí ó sì npín èrè gẹ́gẹ́bí ìṣe wa" Ọba ní ìtẹ́lọ́rùn nlá pẹ̀lú awọn idahun ọmọ dé kùnrin yi ti ó fi pàṣẹ wipe ki àwọn ìdáhùn wọ̀nyí di títàn kálẹ̀ kákiri ìjọba rẹ̀. ó sì fún olórí adarí yi àti olórí pípé ọmọ rẹ̀ ní àwọn ẹ̀bùn iyebíye.

## NÍBITÍ A LÈ FI ÌFẸ́ ÀTI ÌGBẸ́KẸ̀LÉ WA SÍ

Gẹ́gẹ́bí ìtàn tí a kà, ó yé wa ìdí ti a fi níláti tẹ̀lé ìlànà lati lè dé ibi àfojúsùn wa, ṣùgbọn bawo ni a ti ṣe lè pinnu irú ilana lati lè dé ibi àfojúsùn wa, ṣùgbọ́n bawo ni a ti ṣe le pinnu iru ilana ti a nilati tẹ̀lé?

Gbogbo wa ni a ni ìtọ́ni lati tẹ̀lé àwọn ìtọ́ni kan ni gbogbo aye wa. Àwọn àṣà àwùjọ, òfin orílẹ̀ èdè wa, ìrònú, àwọn ìtọ́ni òbí ati ti awọn ẹlẹgbẹ́ wa. Ní ìgbà ilé ẹ̀kọ́ mi, àwọn olùkọ́ má ndarí wa. A má ntẹ̀lé àwọn àṣà tí a gbé lárugẹ tí a tún ngba ìmọ̀ tí a kà nínú àwọn ìwé. Ti a ba kùnà láti tẹ̀lé àwọn adarí wọ̀nyí tí a wá nfi etí si awọn ọkàn wa tí kò ní ìjánu, a lè bá ara wa ni àyè ìdálẹ́bi lati ọ̀dọ̀ alákoso ìjọba kí a sì jìyà tí ó yẹ.

A ni ominira lati yan alaṣẹ́ tí a fẹ́ gbé ìfẹ́ àti ìgbẹ́kẹ̀lé wa lé.

Ó dára kí a tẹ̀lé ìmọ̀ àti aláṣẹ gíga tí ó dára jùlọ láti lè tọ́ wa sí ọ̀nà tí ó ga àti sí àyè ìmọ̀lára Àláfíà. Àwọn ònwòye lati iran de iran ma nmu ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọ̀nà àbáyọ wá si àwọn ìṣòro laye. Bi ìwòye wọn ti dára tó, kò sí èyítí o tí fún wa ní ipa tí ó gbòrò tàbí dé òpin tàbí tí ó pé gẹ́gẹ́bí ti àwọn ìwé mímọ́ Vedic ti India. Gbogbo awọn ònwòye ati awọn ẹlẹ́sìn aye fi gbòngbò múlẹ̀ nínú awọn ìwé mímọ́ wọ̀nyí. Èdè àkọ́kọ́ tí a fi kọ Vedas ni Sánskrítì, èyítí Í ṣe èdè tí ó dára jùlọ láyé. Awọn ìwé mímọ́ wọ̀nyí tí wọn bẹ̀rẹ̀ nínú Ọlọ́run fúnrara rẹ̀ ti di fífi lé àwọn ènìyàn lọ́wọ́ láì yí padà láti ọ̀dọ̀ olùkọ́ lọ sí ọ̀dọ̀ àwọn akẹ́kọ̀ fún ọ̀kẹ́ àìmoye ọdún láti ìgbà ìwáṣẹ̀. A ó mú lati awọn ìwé mímọ́ ti ó daju wọ̀nyí lati fi yànnàná awọn àfojúsùn tí ènìyàn lè ní, ìlépa tí ó ga jùlọ ati òpin ọjọ́ tí ó dájú tí ó tayọ gbogbo àyíǹike ayé lọ.

Àwọn ìwé mímọ́ vedic nkéde pé gbogbo eniyan yálà wọ́n mọ̀ tàbí wọn kò mọ̀, wọ́n nlépa ọ̀kan nínu àwọn ipa mẹ́ta wọ̀nyí. Àwọn àfojúsùn mẹ́ta ati ìṣe tí a nílò láti lè ní wọn ni a yànnàná báyì:

1. Diẹ ninu wa, ni a ntẹ̀lé ipa ìtẹ̀lọ́rùn awọn ẹ̀rí ti ara eyiti a lérò pé yio fun wa ni ìdùnnú. Awọn èrò wọ̀nyí wà gẹ́gẹ́bí ọkàn ati ọgbọ́n orí. Irú ìgbádùn ìrònú ti ara yi ni à npè ní bhukti ní èdè Sanskriti.
2. Díẹ̀ nínú wa nfẹ́ lati ni itọni igbadun ohun ti o wà ninu wa, ki a lépa ipa òmìnira kuro ninu àwọn ìjìyà ayé yi. Irú ominira yi ni a npè ní mukti
3. Ìwọ̀n péréte ninu wa npọ̀ngbẹ lati sin Ọlọ́run pẹ̀lú ìfẹ́ ìfarajì pípé. Ipa ifaraji ìjọ́sìn fun Ọlọ́run ni a npe ní bhakti, tàbí yógà tí àdàpè rẹ̀ túmọ̀ sí àsopọ̀ pẹ̀lú ẹnití ó ga jùlọ nípasẹ ìsìn ìfẹ́.
4. Ti a ba fi ara balẹ̀ ronú lórí awọn ipa mẹ́ta wọ̀nyí, aó mọ̀ pé gbogbo ẹ̀dá ènìyàn ntiraka láti ní ọ̀kan nínú àwọn ìlépa wọ̀nyí.

## NJẸ́ ÀWỌN ÈRÈ TI ARA LÈ MÚ OJÚLÓWÓ ÌDÙNNÚ WÁ BÍ?

Níní ìdùnnú nípasẹ̀ ìlọ́rọ̀ ti ara ni afojusun ti ó gbajúmọ̀ jùlọ ti a mẹ́nu bà nínú ìwé mimọ́ Vedic. Nipa níní ọrọ̀ ati gbajumọ̀ tabi igbadun ti ara, a nlepa lati gbadun ayé wa ninu àyè ìrírí ti ara yi. Ẹnikẹ́ni ninu aye yi lè ní oniruuru ìgbádùn ti ara eyi ti o wà fun ìgbà díẹ̀, ti ìlépa irú ẹni bẹ̀ bá lágbára tó. Lára iwe mimọ Verdic ṣe ilana yi daradara. Awọn ẹsẹ kan pàtó lè ṣe àfiwé igi ti ó fẹ́ lati tẹ́ gbogbo ìfẹ́ wa lọ́rùn bí wọ́n ṣe nṣe ìrànlọ́wọ́ fún àwọn tí ó ní ìlépa ohun ti ara. Gbogbo onírúurú igbadun ti a lè lépa lati ní ni a ṣe àlàyé rẹ̀, pẹ̀lú awọn igbadun ti a le rí ní àwọn àyè míràn pẹ̀lú. Àwọn kan má npe àwọn ayé míran ní "Ọ̀run" nitori ní awọn ọ̀nà kan, wọ́n jọ ara wọn. Ṣùgbọ́n ìwé mímọ́ wipe awọn ayé míràn wọ̀nyí kò wà títí lái ti awọn ọkàn ti o wa níbẹ̀ si níláti padà sí ayé yì.

Ọ̀pọ̀ láyé yi ti wọn kò ni ànfàní lati gbọ́ nipa awọn ilepa giga ti ẹ̀mí, ti wọ́n wà nwá gbogbo igbadun ti ọkan ati ti ara, tabi ti wọ́n nwa igbadun ti ọkàn ati ti ọpọlọ. Ayé ti ara yi wà lati ni iru igbadun yi nipasẹ̀ ọgbọ́n ti ara láti inú ọkàn, ojú, ahọ́n, etí, ikùn ati láti ibi tí a ti nbímọ. Ọkàn ọ̀pọ̀ ènìyàn láyé lónì ní àwọn ilepa igbadun ti ko fi ẹsẹ̀ múlẹ̀. Ṣùgbọ́n kini ipele aṣeyọri ti ẹnikẹ́ni ní? Njẹ́ a mọ ẹnikẹni ti inu rẹ̀ ndun nigbagbogbo bi? Nígbàmíran, idunnu ti nkan ara borí eniyan tí ó fi jẹ́ pé kìkì ironu wọn ni lati bá awọn aini wọn pade gẹ́gẹ́bí ounjẹ, aṣọ ati ilé ìgbé. Síbẹ̀ wọ́n nṣe igbadun awọn idunnu lori ounjẹ ti wọn rí jẹ. Ọlọ́rọ̀ kan lè ní ìrírí ìpele ìdùnnú kan nipa ìrírí ọkọ̀ ìgbafẹ́ ojú omi titun. Ọlọ́rọ̀ ati tálákà jọ ngbadun eré ìtàgé kanna pẹ̀lú àwọn ètò orí ẹ̀rọ móhùnmáwòrán. Lópin rẹ̀, ìdùnnú ọlọ́rọ̀ kò ju ti tálákà lọ. Ṣùgbọ́n ní àyèkáyè tí a bá ba ara wa láyè, a nfẹ́ sọ ìdùnnú wa di púpọ̀. Bi nkan ṣe rí kìí tẹ́ wa lọ́rùn, ìdí ni pé ọkàn, ara ati ọgbọ́n wa kò lè ní ìtẹ́lọ́rùn nítorí wọn kò wà títí lái tí wọn yío sì parun bó pẹ́ bó yá. Ọkàn ni ìdánimọ̀ wa. Ó wà titi laí tí ó sì nmú wa fẹ́ lati jinlẹ̀ si ninu ara wa lati so pọ̀ mọ́ awọn ẹ̀dá ti ẹ̀mí gíga wa. Ní ìpele yi nìkan ni a ti lè rí ìdùnnú tòótọ́.

## ÀWỌN ÈRÈ TI ARA KÌ Í ṢE IPA TÍ Ó TAYỌ JÙLỌ.

Nípa ojúrere, àwọn kan ti bẹ̀rẹ̀ sí ní òye asán ti o wà ninu ìlépa àwọn ohun asán ti ara tí wọ́n si nlépa aláṣẹ tí ó lè darí wọn sí ipa ìmọ̀ tí ó jinlẹ̀. Ní àkókò yí, ènìyàn lè gbọ́ ọ̀rọ̀ mímọ́ gẹ́gẹ́bí Bhagavad – gita, tí àlàyé rẹ̀ njẹ́, "Ọlọ́pọlọ pípé ti kìí kọ́pa nínú ìdàmú, èyítí ó nwáyé láti inú ọgbọ́n ti ara. Ìwọ ọmọkùnrin Kúntì, irú ìgbádùn bí èyí ni ìbẹ̀rẹ̀ àti òpin, nípa bẹ̀, ọlọgbọ́n ènìyàn kò ní ìgbádùn nínú wọn".

Pẹlú ìmọ̀ wipe, ilépa wa tí ó le jùlọ jẹ́ ìgbádùn ti ara ṣùgbọ́n wọn kò ní ojúlówó ìdùnnú tí ó wà fún ìgbà pípẹ́. A lè ní ìfẹ́ ní ọkàn wa láti lè ní òmìnira kúrò ninu àwọn ìfẹ́ ti ara. A lè wá máa bèrè láti wá òmìnira kuro ninu àwọn ìṣe tí ó kún fún àwọn ìgbésẹ̀ ti ó nmú àṣeyọrí tí kò dára wá. Idahun wà fún gbogbo ìgbésẹ̀ gẹ́gẹ́bí ohun kan, tí ó bá mì sí ọ̀tún, yío tún mì sí òsì. Àyè ìdùnnú tí o bá wà wà fún ìgbà díẹ̀, eyiti àìdùn inú yío tẹ̀le. Gẹ́gẹ́bí ọmọdé ṣe ni idunnu ni ìṣẹ́jú kan tí yío sì bú sẹ́kún ní ìṣẹ́jú tí ó tẹ̀le. Tí ìṣe wa bá tilẹ̀ ni ìgbésè ti o tọ̀nà, ṣugbọ́n ti àbájáde rẹ̀ kò bá dára, ìdùnnú ti à nní ìrírí rẹ̀ wà fún ìgbà díẹ̀, tí ìdàmú sì ntẹ̀le. A wa pinnu pe ominira kuro lọwọ ìjì tí ó njà sí ọ̀tún àti òsì ni ó yẹ kí ó jẹ́ ìlépa wa. Síwájú si, ipa ọ̀na ti ara kò mú ìgbádùn ti ó npẹ́ wá, ní pàtó ó jẹ́ èrèdí ìgbèkùn.

Ohunkohun ti ó ba lè díbàjẹ́ jẹ́ ohun ti ara kìí ṣe ti ẹ̀mí. èrè ti ara má nwà fún igba díẹ̀, pẹ̀lú ìdùnnú tí kò lọ títí. Àwọn iwe mimọ Vedic sọ fun wa wipe a ju ohun ìgbà díẹ̀ lọ, tabi ohun ti ara. Àwá ní ẹ̀mí ti o wà titi laí nínú ara wọ̀nyí, nitorina, ara kíkú ati igbadun ti ara kò fún wa, tàbí ọkàn wa ní ojúlówó ìdùnnú.

Bi a ṣe nronu lórí àwọn òtítọ́ wọ̀nyí, ìwòye wa yio máa gbòrò si, ti a si le yàn láti gba ipa ti inú. Gẹ́gẹ́bí ọlọ́pọlọ pípé ti ẹ̀mí, kílódé tí a ṣe fẹ́ ní ìtẹ́lọ́rùn sí nkan yẹpẹrẹ?

**IPA Ọ̀NÀ ÒMÌNIRA**

Kini idi ti ẹnikẹni ninu wa kò ṣe fẹ́ kú? Ẹni nla kan wipe ìyàlẹ́nu ni pé láyé yì, níbi gbogbo láyìká wa, ní gbogbo àyè láyé, eniyan pẹ̀lú àwọn igi ati ẹranko ni wọ́n nkú, síbẹ̀, a kò gbàgbọ́ pé ikú yío tọ̀ wá wá.

Àwọn ìwé mímọ́ Vedic wípé Ọkàn wa wà títí lái nínú ara nípa bẹ kìí kú. Wọn tun fihan wipe ọkàn kún fún ìsimi, nitorina ó di dandan nínú ọkàn wa láti wá ẹ̀dá àlááfíà tòótọ́ tí ó sì ga èyítí ó sì jẹ́ ọ̀rọ̀ ìdùnnú.

Ẹ̀dá ọkàn ni láti wá Àláfíà ninu ayeraye àkókò yí, tí ó ní òmìnira lọ́wọ́ àtijọ́ àti ọjọ́ ọ̀la ati kúrò ninu àjàgà àwọn ìfẹ́ ti ara. Ẹ̀dá ọkàn tí kò ní àkóso yà ní àrà ọ̀tọ̀. Níṣe ni kì Í ní ìsimi, ó kún fún ìfẹ́ nkan, tí ó nfi igbagbogbo máa ṣe ètò fún idunnu ìgbádùn ọjọ́ iwájú. Nítòótọ́, ipa ọ̀nà sí ominira kúrò ninu àwọn ìjìyà ati ìbànújẹ́ ìgbé aye ti ó dàbí ẹnipé ó nfanimọ́ra, lótìtọ́, ọ̀pọ̀lọpọ̀ wa nlépa èyí tí a sì nṣe làálàá, àti ìfiyà jẹ ara ẹni láti ní àfojúsùn yí.

Ìlépa òmìnira kúrò ninu àwọn ìṣe àti àtubọ̀tán wọn jẹ́ àfojúsùn ti ó ní ọlá nínú tí ó sì ga jù láti máa gbádùn àwọn igbadun ti ara. Ominira kuro ninu

igbiyanju igbadun ti aye yi jẹ́ ohun ayeraye ti ọkàn. Eniyan lè dé àyè yí nipa títẹ̀lé àwọn ìṣe mẹ́rin wọ̀nyí:-

1. Ṣe ìyàtọ̀ lárín ohun tí ó wà fún ìgbà díẹ̀ tàbí díbàjẹ́ àti èyítí ó wà láíláí tàbí ti ẹ̀mí
2. Lòdì sí gbogbo ìfẹ́ fún àwọn èrè ìgbà díẹ̀, àti ìgbádùn ayé yi àti àwọn ohun gíga ní àwọn ayé ti ọ̀run, èyítí a ṣe àpèjúwe gẹ́gẹ́bí ohun ìgbà díẹ̀ nínú Vedas.
3. Fara jì fún àti di ẹni òmìnira.

Bí a ṣe sọ ṣíwájú, àwọn iwe mimọ́ Vedic dàbí igi tí ó fẹ́ láti fún wa ní ohunkohun tí a bá fẹ́. Nwon ma ntan ìmọ́lẹ̀ si oniruuru afojusun pẹ̀lú ìyànnàná àwọn ètò ìgbésẹ̀ tí ó yẹ láti ní wọn.

Ominira jẹ́ àyè ẹ̀rí ọkàn mímọ́ níbití ọkàn ti mọ ara rẹ̀, nípa bẹ́ẹ̀ ó lè ṣe àwárí ara rẹ̀. Ẹ̀dá ọkàn òmìnira yẹ kí ó pé, kí ó ní ìtẹ́lọ́rùn pẹ̀lú àṣeyọrí. Ọkàn ngbé nínú ìsimi ní òun nìkan, láìsí ìfẹ́ fún igbadun ohunkohun ninu ayé ti ara yi.

Ìyàlẹ́nu ninu ọkàn bí èyí yío jẹ́ pẹ̀lú ìrànlọ́wọ́ àpẹrẹ ti ara. Ká ní wípé a ṣẹ̀ṣẹ̀ jẹ ounjẹ́ àdídùn kan tán, bí a ṣe wá dùbúlẹ̀ sí orí ibùsùn, pẹ̀lú àláfíà, ti a ngbadun àwọn mọ̀lẹ́bí, inu wa yio dùn dé inu nítori àwọn ọgbọ́n wa ní ìtẹ́lọ́rùn ni àkókò nà ati wipe kò sí ìjìyà, a ní ìmọ̀lára ohun ti ó nṣẹlẹ̀ lọ́wọ́lọ́wọ́. Kò sí làálà tabi ètò ṣíṣe fún idunnu ọjọ́ ọ̀la, bẹ́ni a kò ránti ohunkohun láti àtẹ̀hìnwá. Dípò bẹ̀, a ngbádùn àkókò nà nípa àìsí ìjìyà ayé yì, tí ó ṣòro, ati ọkàn tí ó nbèrè nkan di títì pa fún ìgbà díẹ̀. Ní ayé yì, a rí ara wa wípé inú wa ndùn. Irú ipò yí jẹ́ àfiwé ìmọ̀lára ẹnití ó gba òmìnira kúrò ninu àwọn ìfẹ́ inú nítorí fún ìgbà díẹ̀ kò sí ohun tí a fẹ́. Pẹ̀lú ìtẹ́lọ́rùn yí, a mọ rírì àkókò nà. Àpẹrẹ yí jẹ́ ohun asán, nítorí àkókò ìtẹ́lọ́rùn kò dúró dáradára, ó sì wà fún ìgbà díẹ̀. Ní ọ̀nà kejì, ọkàn tí ó ṣe orí rere ti ó gba ominira ninu oko ẹrú ìfẹ́ ìrírí, ga ju ìtẹ́lọ́rùn gíga lọ. Síwájú si, Àláfíà yí wà títí láí.

## ÌRÒNÚ LÓRÍ ÀKÓKÒ

Ninu aye yi, ipele mẹta ló wà: àná, òní àti ọ̀la. Lákọ̀tán, ó wá ṣòro fún wa lati maa gbé ní àkókò ti òní nitori ironu inu rẹ̀, nítori ó kún fún ojuse ti o ga ju agbara wa lọ. Bẹ́ná ni a tun ma njìyà ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìdùnnú láti ọ̀dọ̀ àwọn eniyan, ojú ọjọ́ tí kò dára tàbí láti ọwọ́ ọkàn wá. A má nronú ipò ìdùnnú síwájú si láyé ju àwọn àkókò tí ó le, nípa bẹ́ẹ̀ ọkàn má nronú ètò, àlá ọjọ́ ọ̀la láti lè sá fún ipò àìní ìdùnnú àkókò yí. Nígbàgbogbo ni ọkàn má nronú láti lè kojú àwọn ipò ti ara fun anfani wa àti lati lè lo àwọn ohun ti ara fún ìtẹ́lọ́rùn ti ara ẹ̀mí. Igbadun nikan ni ọkàn nfẹ́.

Gbogbo wa lo fẹ gbádùn, ìṣẹ̀dá wa ni èyí. Ni gbogbo ọjọ́ ayé wa, a gbádùn gbogbo àkókò. Èyí ni ìlàkàkà ìgbàgbogbo wa.

Ẹ̀dá ọkàn ti ara àti ti ọkàn ti ẹ̀mí yàtọ̀. Ọkàn jẹ́ ohun èlò láti dé abala ẹ̀mí. Ẹ̀mí kò ní ìfẹ́ fún ìtẹ́lọ́rùn bíkòṣe láti máa gbádùn nigbagbogbo; ṣùgbọ́n ti ọkàn yàtọ̀, ó kún fún ìfẹ́ láti ṣe nkan. Nitori nipa ti ara, a má nfẹ́ lọ pẹ̀lú ọkàn ju ẹ̀mí lọ, a má nní ìpèníjà ìjákulẹ̀ nígbàtí ìrètí wa kò bá wá sí ìmúṣẹ. Nigbana, tí ojú wa bá là ni a ó wá ní òye òtítọ̀ tí ó jinlẹ̀ si. Nígbàyí ni ènìyàn yío wá wọ inú ìmọ́lẹ̀ lọ.

## Ó RÉKỌJÁ ÒMÌNIRA

Ní àkókò ìdàgbàsókè yí, ohun kan wa lati ronu lé lórí. Ìwé mímọ́ gbà wá nímọ̀ràn lati rin ìrìn àjò ti o jinle si inu ìmọ̀lára tí ó kọjá ipò Àláfíà kuro ninu gbogbo aye yi. Otitọ ibẹ̀ ni pe kí a ni ominira kuro ninu gbogbo ìjìyà jẹ́ abala tí ó lòdì sí ojulowo ominira. Eyi ti ó tọ̀nà níbẹ̀ ni anfani ti o wà lati ni ibaṣepọ̀ ati ibaṣepọ̀ ìfẹ́ pẹ̀lú Ọlọ́run. Tí, ní ayé òmìnira, ti á tún nní ìdánimọ̀ wa gẹ́gẹ́bí eniyan láyé yì, yàtọ̀ sí ki a ṣe ìdánimọ̀ wa gẹ́gẹ́bí ojúlówó ìránṣẹ́ Ọlọ́run, báyì, a kò Ì tí dé ibiti à nlọ. Irú ominira báyi kìí ṣe ojulowo  nitorina, kìí ṣe ìlépa wa tí ó ga jùlọ.

Àìní ìjìyà ti ara ni abala òdì ayọ̀ wa tí ó ga jùlọ. Àyè tí ó ga jùlọ ní ìtanijí fún ìbáṣepọ̀ wa pẹ̀lú Ọlọ́run fúnrara rẹ̀ ní ọ̀nà ìfẹ́ àti ayọ̀. Ìsimí ti o ti inu àìpé òmìnira wá ní akùdé nítorí inú ọkàn ló wà, ó jẹ́ ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú ara rẹ̀ nìkan. Èyí jẹ́ nkan ìmọtara ẹni nìkan nitori ìfẹ́ láti sin ẹlòmíràn kíí ṣe Pàtàkì. Ní ipele yi, a kàn wọ inú abala Alafia ní inú wa ni, láìtíì wọ inú agbami ìgbàpadà àti ìbáṣe pọ̀ ìfẹ́ pẹ̀lú ọkàn tí ó ga jùlọ.

Àyè tí ó ga jùlọ ni a lè fi wé èyítí ó pé, tí kò ní àbùlà, tí ó ní ìfẹ́, tí ó sì ní ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú Ọlọ́run tìkalára RẸ̀. Ọ̀kẹ́ àìmoye orin ni wọ́n fi ògo fún ọdún ìbáṣepọ̀ láyé yi, ṣùgbọn awọn orin àti àwọn àkókò ìfẹ́ wọ̀nyí kàn wà fun igba díẹ̀ ni. Bí ó ba tilẹ̀ jẹ́ wípé àwọn àkókò ìbáṣepọ̀ ìfẹ́ yi bá fẹ́ wà fún ìgbà pípẹ́, ikú yío mu wá sí òpin. Ọkàn nfẹ́ láti ní ìbáṣepọ̀ pípé tí yío mú ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ ìtẹ́lọ́rùn wá.

Ìbáṣepọ̀ ìfẹ́ gbogbo nílò ìlọ́wọ́ sí ẹni méjì. Ìfẹ́ ní ìṣe nínú ìgbékalẹ̀ rẹ̀. láti fi ìfẹ́ hàn sí ẹnikan tabi si ohun kan. Ọ̀kan lara ìsimi ni ìrírí ayọ̀ ọkàn ominira kuro ninu awon ìbànújẹ́ ayé. Orísun ìsimi tí ó ga jùlọ wá láti itaniji ọkàn àti ìbáṣepọ̀ ayeraye pẹ̀lú Ọlọ́run. Irú ìsimi yi kò ní àlà rárá.

## KÍNI OJÚLỌ́WỌ̀ ÌFẸ́?

Láti ìbẹ̀rẹ̀ ayé, ni ọkàn ti npohùn réré ẹkún fún ìfẹ́. Ìfẹ́ ni agbára tí ó ga jùlọ láyé, gbogbo wa ni a sì fẹ́ tọ wò lọ́nà kan tàbí òmíràn. A kò fẹ fún

ìgbà díẹ̀ ṣùgbọ́n títí lái. Èyí gan ni ogún ìbí wa. A lè ni ohun gbogbo láyé, ṣùgbọ́n kí ohun tí ó ṣe koko jùlọ èyí tí kìí ṣe láti fẹ́ràn àti láti ní ìfẹ́ ní akùdé. Agbára ìfẹ̀ kò ní òdiwọ̀n. Ìfanimọ́ra ìfẹ́ ni ìpìlẹ̀ àti ohun alágbára jùlọ tí a rí ninu àyèkáyè láyé. Pẹ̀lú ìfẹ́ tòótọ́, a lè gbàgbé kí a sì mú ohun gbogbo míràn kúrò. Ti ó bá tako ìgbékalẹ̀ ìfẹ́, irú ẹni bẹ́ẹ̀ ti gba ìjákulẹ̀. Ìfẹ́ ní ìgbékalẹ̀ tí ó fi ẹsẹ̀ múlẹ̀ jùlọ.

Kọ́kọ́rọ́ sí òye ìyàtọ̀ larin oriṣi Alafia tí a mẹ́nu bà ṣíwájú- èyí tí a ní èyítí ó ní akùdé àti èyítí ó wáyé láti inú ìfarajì fún Ọlọ́run ni wípé kí a mọ iyì ẹ̀dá ìfẹ́. Ìfẹ́ jẹ́ ohun ìṣe nípa bẹ́ a níláti ro ti ẹnití a ó fẹ́ràn. Isimi ti a nri láti inú ominira tí ó ní akùdé ti inú ìdákẹ́ ìpòrúuru ọkàn wá, eyítí ó nfun wa ní ipò ìmọ̀lára Àlàfìà tí kò ní ìfẹ́ sí àwọn ohun ti ara. Ṣùgbọ́n a kò lè pe ipò yí ní ìfẹ́, kò tilẹ̀ ní ohun kohun lati ṣe pẹ̀lú ìfẹ́. Ninu rẹ̀, a kò lè rí ọkàn ìfẹ́ gbígbóná. Ipò gíga jùlọ ti ìfẹ́ èyítí ó pé, èyítí ó wà lótìtọ́ lárín ọkàn àti Ọlọ́run, àwọn méjèèjì jẹ́ ẹ̀dá ayérayé.

Ẹ̀dá wa báyì nítori a ti ni ọmọ púpọ̀ ti njẹ́ kí a máa lépa agbára Ọlọ́run fun ara wa ti ó wá jẹ́ ki a pàdánù ìtẹ́wọ́gbà ìwàláàyè RẸ̀ tí ó rẹwà. Ìdí ni wipe a nlepa agbara ati ògo ara wa laye. Ìlépa awọn ohun ti ara wọ̀nyí nmu wa padanu laye wa ohun tí ó ṣe iyebiye ati iyanu ati ẹniti Í ṣe Ọlọ́run. Ohun buburu yì ti mú wa kuro ninu ohun ti ẹ̀mí lọ si inu ohun ti ara nibiti ojulowo ìfẹ ti kuro fun ojulowo ìbẹ̀rù. Ẹniti o nṣe àwárí nítòótọ́ yio di ẹnití a ṣì lọ́nà fún ìgbà pípẹ́, láìpẹ́ yio gbé orí rẹ̀ sókè láti bèrè wípé kíni ìdánilójú ìfẹ́ ayérayé.

## IPA Ọ̀NÀ ÌFẸ́ ÀTÒKÈWÁ

Ipa ọ̀nà ìfarajì àtí ìfẹ́ sí ìsìn Ọlọ́run(Bhakti) ni a ṣe apejuwe rẹ̀ daradara ninu iwe mimọ Vedic. Awọn ẹni nla atijọ ní òye àiní àtọ̀runwá àwọn eniyan tí wọ́n si ti tọ́ wa bí a ti ṣe lè ní ìtẹ́lọ́rùn ti ó pé nípa àsopọ̀ pẹ̀lú olùkọ́ àgbà ati Oluwa wa ọ̀wọ́n. Ninu itan ọba ti ó fẹ́ rí Ọlọ́run, a bèrè lọ́wọ́ ọba bí ọ̀rá bá wà nínú wàrà, ó sì dáhùn, “Bẹ́ni ṣùgbọ́n ilana nilati di títẹ̀lé lati lè ri “Bẹ́na ni ti a ba fẹ́ ṣe ìtanijí ibáṣepọ̀ ayeraye wa pẹ̀lú Ọlọ́run, a nilati tẹ̀lé awọn àlàkalẹ̀ ilana lati ẹnu awọn aṣíwájú kí a sì gbọ́ràn si àwọn itọni wọn. Laisi awọn itọni ti ẹ̀mí yi, a kò ni lè jí si àwọn ibaṣepọ ti ẹ̀mí. a kò lè ṣe èyí pẹ̀lú agbara wa nikan. Agbara tí ó kọja ti ayé yi ni a nílò. Aanu ati ore- ọ̀fẹ́ àtòkèwá ṣe Pàtàkì. Lati ibo àti báwo ni a ti ṣe lè ní agbára yi?

## NIBITÍ A TI LÈ RÍ AGBÁRA

Láti lè tọ ipa ìfẹ́ àtòkèwá, a nílò ìmọ̀, àtìlẹhìn ati agbara lati ọ̀dọ̀ ẹnití ó wà ní ọ̀nà na. Ẹnití ó jìn sí inu kànga nílò iranlọ́wọ lati ọwọ́ ẹnití o dúró daradara pẹ̀lú okùn lọ́wọ́ rẹ̀, bẹ́ ná ni ìrànlọ́wọ́ kúrò nínú ipò ìjìyà wa

yió wá lati ọ̀dọ̀ ẹnití ó mọ̀, tí ó sì ní òye àwọn òtítọ́ Pàtàkì láyé. Kò sí ọ̀nà míràn kúrò nínú ìṣòro wa! A nilati wá irú ẹni bẹ́ẹ̀ rí. Pẹ̀lú ìlépa yi ní ọkàn wa, pẹ̀lu ìdánilójú aṣojú Ọlọ́run yẹn yio wá láìpẹ́. Ẹyo ojúṣe wa nìkan ni kí a ṣetán lati pade ẹni nà. nígbàná nípa ètò àtòkèwá, aó mú wa tọ̀ọ́ lọ kíákíá.

## ÌFẸ́ ÀTI ÀWỌN ÌBÁṢEPỌ̀

Àwọn iwé mímọ́ Vedic ṣe apejuwe orukọ Krishna gẹ́gẹ́bí orúkọ Ọlọ́run ti ó ga julọ. Ni Sanskriti, Krishna túmọ̀ sí "Ẹnití a fẹ́ràn jùlọ"Orukọ Ọlọ́run Sankriti fún wa ní òye sí ẹniti ó jẹ́. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé Sankriti ní ìdí fún ohun gbogbo ati otitọ́ tí o ga jùlọ, ó ni ibaṣepọ̀ iyanu tímọ́tímọ́ pẹ̀lú ọ̀pọ̀ mọ̀lẹ́bí àti ọ̀rẹ́ ní inú ayé rẹ̀ nínú ẹ̀mí ayeraye pàpá ní Vrindavana, ilé rẹ̀ tí ó rẹwà tí ó sì dára jùlọ nínú gbogbo àwọn ibùgbé RẸ̀. Àwọn ọ̀rẹ́ ati awọn mọ̀lẹ́bí rẹ̀ wọ̀nyí nwà pẹ̀lú RẸ̀ nígbàtí ó bá nṣe oniruuru iṣẹ́ ìyanu tí ó má nya ènìyàn lẹ́nu. Awọn ìṣe wọ̀nyí ni àwọn ẹni nlá ti ṣe àlàyé rẹ lẹ́kùnrẹ́rẹ́ ninu awọn àṣàrò wọn, wọ́n ti ní àjọṣepọ̀ ìfẹ́ ìjìnlẹ̀ lárín Krishna àti àwọn tí wọ́n súnmọ́.

Ilé ayeraye wa wà nínú ayé ti ẹ̀mí pẹ̀lú Krishna. Níbẹ̀ ni aó ti rí ìrírí Alafia giga ati òye ìbáṣepọ̀ ayeraye tí ó lágbára pẹ̀lú RẸ̀. Àwọn tí wọn npọ̀ngbẹ sí òmìnira akùdé yío pòngbẹ lati jẹ́ Krishna fúnrara rẹ̀. Èyí kò ṣeéṣe- nitori èmi ni èmi, ìwọ ni ìwọ, ìwọ kò lè jẹ́ Ọlọ́run tí ó dá àwọn ohun tí kò ní òdiwọ̀n àti bẹ́ẹ̀bẹ́ lọ. Alafia ominira alákùdé jẹ́ ti ìmọ- ta- ra-ẹni nìkan ati wipe láìsí ìpàṣípàárọ̀ yío ní akùdé. Ṣùgbọ́n ti a ba wọ inú ìbáṣepọ̀ ìfẹ́ pẹ̀lú Krishna pẹ̀lú ọkàn ìsìn si, Alafia ti a ni yío wà láíláí. Àfojúsùn gbogbo ìṣè wa ni lati sọ ìmọ̀lára wa tí ó dúró sí ojú kan di akúrẹtẹ̀, èyí ni mímọ ẹ̀dá tòótọ́ wa gẹ́gẹ́bí olùfẹ́ Krishna ìránṣẹ́ ayérayé.

Nípa kíkà nípa RẸ̀, ati nipa gbígbọ́ nípa RẸ̀ láti ẹnu àwọn ẹlòmíràn pàápà àwọn tí wọ́n ní ìmọ̀ nípa ẹ̀dá ológo RẸ̀, nígbàgbogbo ni a ó ní ìwúrí lati sunmọ si nígbànà, nigbati a ba fi ara yi sílẹ̀ ní àkókò ikú, aó wà pẹ̀lú RẸ̀ láíláí.

## BÍ A TI ṢE LÈ ṢE ÀṢÀRÒ

Ni akoko wa yi, a ṣe ori ire wipe ilana ti a júwe láti ni ìbáṣepọ̀ Alafia pẹ̀lú Ọlọ́run nipa wíwá ara ẹni rí, ni láti kọ orúkọ mímọ́ RẸ̀ ní orin. Jesu Kristi papa bẹ̀rẹ̀ àdúrà mímọ́ RẸ̀ tí ó gbajúgbajà jùlọ ni ó ti fi ògo fún orúkọ Ọlọ́run: "Ọ̀wọ̀ ni fún orúkọ RẸ" Krishna ti fi gbogbo agbara ati ipá sí àárín orúkọ RẸ̀ pẹ̀lú àwọn anfani lati gbádùn àwọn ibaṣepọ̀ alárinrin pẹ̀lú RẸ̀. Ìlànà orin kíkọ yi nṣe iyipada bi ìgbàgbọ́ wa si ti ndàgbà si ná ni agbára àwọn orúkọ mímọ́ RẸ̀ yio maa tan ìmọ́lẹ̀ sí òye wa. A lè ní ìrírí èyíkéyì àfojúsùn mẹ́tẹ̀ẹ̀ta tí a ṣe àlàyé wọn ṣáájú nípa orin

kíkọ yi. Tí kò bá dá ọ lójú, dan wò fúnra ra rẹ kí o sì jẹ ìgbádùn àbájáde rẹ ní kíkọ orúkọ Ọlọ́run tí ó lágbára jùlọ, a ó bẹ̀rẹ̀ ìlànà síso ara wa pọ̀ láíláí pẹ̀lú Ọlọ́run tàbí Krishna. Orin nla ti ìtúsílẹ̀ yi ni a npè ní Maha-mantra. Ó lọ báyì:-

| | | | |
|---|---|---|---|
| Hare | Krishna | Hare | Krishna |
| Krishna | Krishna | Hare | Hare |
| Hare | Rama | Hare | Rama |
| Rama | Rama | Hare | Hare |

Tí a bá nkọ àwọn mantra yi, dajudaju ao ní ìrírí òye gíga. Kí a fi pẹ̀lẹ́pẹ̀lẹ́ pẹ̀lú àṣàrò kọ orin yi, nítòtọ́ kíkọ́ nígbàkugbà, níbikíbi ati ní àyèkayè nmú Àláfia nlá wà. Orin kíkọ yi ngbé wa lọ sí inú odò ìfẹ́, paapa tí a bá paá pọ̀ mọ́ ìtọ́ni lati inu iwe mimọ àti ọgbọ́n lati ọ̀dọ̀ àwọn ti wọ́n ti ni ìbáṣepọ̀ ìfẹ́ pẹ̀lú Krishna.

Orúkọ Ọlọ́run pọ̀, gẹ́gẹ́bí Jèhófà, Allah, Buddha, Yahweh, Rámà àti Krishna. Nínú àwọn orukọ́ mímọ́ wọ̀nyí, ìwé mímọ́ verdic ṣe àpèjúwe Krishna ati Rámà gẹ́gẹ́bí èyítí ó dára jùlọ láti kọ lọ́rin fún àṣeyọrí àti ànfàní tí ó dára jùlọ.

**NÍ ÀKÓTÁN**

Ìṣẹ̀dá ọkàn ni láti gbádùn. Ìlépa àti àfojúsùn wa láyé ni ìdùnnú pátápátá. Ọ̀nà mẹ́ta ni a ti má ngbìyànjú láti rí èyí:

1. A ma ngbadun igbadun wa ìgbà díẹ̀ nipasẹ gbogbo ọgbọ́n ti ara wa.
2. A ngbádùn ìkọ̀sílẹ̀ tàbí ìlépa fún òmìnira nípasẹ̀ ọgbọ́n inú wa.
3. À ngbàdúrà nípasẹ̀ ọgbọ́n ti ẹ̀mí àtètèkọ́ṣe wa gẹ́gẹ́bí ìránṣẹ́ Ọlọ́run tí ó fi ara jì - Olúwa Krishna.

Gẹ́gẹ́bí ẹnìkọ̀ọ̀kan, àwọn ipa mẹ́ta wọ̀nyí kò yọrí sí àfojúsùn kannà. Ipò ìgbádùn méjì àkọ́kọ́ nípasẹ̀ ọgbọ́n ti ara àti òmìnira ti ara kò mú wa lọ sí ipa òtítọ́, ṣùgbọ́n ìbáṣepọ̀ pípé àìlábùlà àti ìbáṣepọ̀ ìfẹ́ pẹ̀lú Krishna fúnrara rẹ̀.

Ipele ìgbádùn tí à nrí láti ipa kìní kéré jọjọ sí ìkejì. Lórí ìgbéwọ̀n Àláfíà, ipa kejì kò tilẹ̀ lè dúró nígbàtí a bá nsọ nípa ipa kẹta; nibiti a ti nṣe ìtanijí ìfẹ́ ìbáṣepọ̀ wa pẹ̀lú Krishna. Ọlọ́run fúnrara rẹ̀. Ẹnití ó nṣe èyí nìkan ni òye òtítọ́ yí lè yé.

Ọ̀rọ̀ tí a yànnàná rẹ̀ nínú ìwé pélébé yi jẹ́ díẹ̀ nínú ọ̀pọ̀ ìmọ̀ tí ó wà nínú àwọn ìwé Vedic nibiti a ṣe alaye díẹ̀ ninu àwọn ìwé mímọ́ yi ní ọ̀nà tí ó

rọrùn. Nigbati o bá nka ìwé yi, tí o sì bèrè ìbéré si lọ́wọ́ ẹnití ó ní ìfọkànsì Krishna, a jẹ́ wípé ìwé yi ti ṣe àṣeyọrí.

Tí o bá fẹ́ mọ̀ nípa àwọn àkòrí wọ̀nyí, ìsìn Hare Krishna ti túmọ̀ ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ìwé Vedic sí èdè òyìnbó àti àwọn ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn èdè míràn fún ànfàní ayérayé. Àwọn ìwé yi wà níbigbogbo, kìkì kí o bèrè fún ọ̀kan, bí idán, yío tètè tẹ̀ ọ́ lọ́wọ́.

**Hare Krishna.**

A bi ní ọdún 1926 ni Bilhar, India ní ẹ̀bá odò omi mímọ́ Ganges, Shrila Narayan maharaj jẹ́ ẹnití gbogbo eniyan mọ̀ gẹ́gẹ́bí òǹkàwé tí ó ní àṣẹ tí ó ní òye èrèdí àwọn ìwé India àtijọ́. Ó túmọ̀ wọn sí èdè Hindu tí ó sì sọ̀rọ̀ le lórí. O lè ní Sanskriti ọgbọ́n àti àwọn àkọsílẹ̀ àtijọ́ Bengali nípa bẹ̀ àwọn àkọsílẹ̀ Vedas àtijọ́ kò parun.

Shrila Maharaj ṣe ìdánilẹ́kọ̀ lórí èròngbà Vaishnava kákiri India fún ó lé ní ogóji ọdún kí ó tó lọ sí ìwọ̀ ọrùn ní ọdún 1996, láti ìgbànà ni ó ti nlọ kákiri àgbáyé ní ó lé ìgbà mẹ́ẹ̀dógún tí ó nṣe ìtànkálẹ̀ ojúlówó Bhakti ti Shri Chaitanya Mahaprabhu.

Wọ́n fun ní oyè "Aṣojú Àláfíà" ni Birmingham, U.K. ní ọdún 2002 fun ìfara ṣiṣẹ́ rẹ̀ fún ọmọnìyàn fún ìtẹ̀síwájú òye nínú ẹ̀mí. Ó tún jẹ́ adarí nínú ìmúpadà bọ̀ sípò ọ̀pọ̀ ìtàn àti àwọn ohun mímọ́ ní India. Ìfẹ́ àìlẹ́gbẹ́ rẹ̀ jẹ́ kí ìfẹ́ rẹ̀ wà nínú ọ̀pọ̀ àwọn ọ̀rẹ́ rẹ̀ àti àwọn akẹ́kọ̀ rẹ̀ pẹ̀lú; àwọn ẹnití ayé wọn yí padà nípasẹ̀ "ìsúre àtọ̀runwá" rẹ̀ fún wọn

Ní ọjọ́ kọkàndínlọ́gbọ̀n oṣù Kejìlá ọdún 2010, ó parí àkókò rẹ̀ láyé yì tí a sì pàdánù ìwàláàyè rẹ̀. Àwọn ẹ̀kọ́ iyebíye rẹ̀ wà títí lái tí wọn yío sì máa tàn gẹ́gẹ́bí ìràwọ̀ láti máa tọ́ wa sí ọ̀nà ìjọsìn fún ìgbà pípẹ́.

**(BACK COVER)**

**s**

Gbogbo ìgbésẹ̀ láyé ènìyàn jẹ́ àsopọ̀ ìṣe àti ìdáhùn .

Àwọn ìgbésẹ̀ ti ara ntẹ̀síwájú nípasẹ̀ irú àwọn àsopọ̀ bẹ̀, èyítí ó nyọrí sí ìfẹ́ láti jinlẹ̀ si nínú ìmọ̀ láyé àti láti gba òmìnira kúrò nínú ìjìyà ti ara. Nígbàtí èyí bá ti ṣẹlẹ̀, àsopọ̀ míràn wà, ipa ọ̀nà ìjọsìn tí ó rékọjá Òmìnira.